JOURNAL OF INDIGENOUS LANGUAGES

Jozac Publishers

Vol. 3, No. 1, 2025
**DOI:** https://doi.org/10.5281/zenodo.17987700
**Website:** http://journals.jozacpublishers.com/jil

***Type of the Paper: (Journal Article)***

# Àtúngbéyẹ̀wò Ìlò Àti Ìṣesí Àwọn Ọ̀rọ̀ À-So-Ọ̀rọ̀-Pọ̀ Ní Èdè Yorùbá

**Olabode Thomas Abimbola[1*]**
[1*]Department of Linguistics, African Languages & Communication Arts, Lagos State University (LASU), Ojo / Faculty of Arts, Lagos, Nigeria. olabodeabimbola9@gmail.com / olabode.abimbola@lasu.edu.ng **ORCID:** https://orcid.org/0009-0004-2580-8185

Correspondence: olabodeabimbola9@gmail.com

**Received:** July 16, 2025; **Accepted:** September 23, 2025; **Published:** December 19, 2025

**Àṣamọ̀:** Ninú gírámà èdè Yorùbá, àwọn onímọ̀ gírámà ṣe àkíyèsí pé àwọn ọ̀wọ́ ọ̀rọ̀ kan wà tí wọ́n máa ń lò láti fi so ọ̀rọ̀, àpólà tàbí gbólóhùn méjì pọ̀. Ẹnu kò lórí ọ̀rọ̀-àsopọ̀ ti ẹyọ ọ̀rọ̀ àti àpólà. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ọ̀wọ́ àwọn onímọ̀ kan náà tilẹ̀ sọ pé kò sí ohun tí a lè pè ní ọ̀rọ̀ àsopọ̀ tí ó ń so gbólòhùn pọ̀, àwọn onímọ̀ mìíràn sì gbà pé ó wà. Ohun tí a fẹ́ tẹpẹlẹmọ́ náà ni láti ṣàgbéyẹ̀wò ìlò ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ọ̀rọ̀-àsopọ̀ wọ̀nyí, kí a mọ iye wọn, àti àwọn òté tó de ìlò wọn nínú èdè Yorùbá. A ṣe àkójọ àwọn détà lóríṣìíríṣìí láti inú àwọn onírúurú ìwé ti wọ́n kọ lédè Yorùbá àti ọ̀rọ̀ ẹnu àṣàyàn àwọn tí ń sọ èdè Yorùbá. A kò ṣàmúlò tíọ̀rì kankan nínú iṣẹ́ yìí kí a lè walẹ̀ jìn lórí àpèjúwe ìṣesí àtì ìhùwàsí àwọn ọ̀rọ̀-àsopọ̀ wọ̀nyí. Ohun tí a ṣe ni pé, a ṣàpèjúwe ìlò àti ìṣesí àwọn ọ̀rọ̀-àsopọ̀ ni. A rí i pé ọ̀rọ̀-àsopọ̀ Yorùbá wà ní abẹ́ ìsọ̀rí wúnrẹ̀n aṣegírámà nítorí àwọn àbùdá ìsọ̀rí náà tó pinminrin sínú rẹ̀. Bí a bá gùnlé ìlò àti ìṣesí wọn, a lè pín ìsọ̀rí ọ̀rọ̀-àsopọ̀ Yorùbá sí ọ̀wọ́ méjì gbòòrò: àkọ́kọ́ ni ọ̀rọ̀-àsopọ̀ tí ó pín sí i: ọ̀rọ̀ a-so-ọ̀rọ̀/àpólà-pọ̀ àti ọ̀rọ̀ a-so-gbólóhùn-pọ̀. Èkejì ni ọ̀rọ̀-a-so-èjì-èrò-pọ̀ tàbí ọ̀rọ̀-asojú-sòdì-pọ̀/elérò ajárètí, ìsọ̀rí yìí náà pín sí: alábala méjì àti aláwẹ́ kan.

**Kókó-ọ̀rọ̀:** Ìsesí, Ọ̀rọ̀-àsopọ̀, Òté-ìlò, Wúnrẹ̀n aṣegírámà, Yorùbá

**Abstract**: In Yoruba grammar, scholars have noted that there is a class of words which are used to connect words, phrases, and sentences together. Scholars seem to agree on the presence of lexical and phrasal conjunctions. Despite the fact that some scholars opined that there is nothing like a sentence conjunction in Yoruba, some scholars agreed that there is a sentence conjunction in the language. This work is not concerned with arguments about argument on the presence of sentence conjunctions or not. The main concern of the present work is to re-examine how each connective/conjunction is used, how many of them are used in numbers, and their usage constraints in the grammar of the Yoruba language. Syntactic structures are collated from various grammar texts and books written in the Yoruba language. No grammatical theory is adopted so as to give a detailed description of connective items' syntactic behaviours in actual usage. It was discovered that conjunction is a sub-class of functional items based on the prepondrance of grammatical features found in the words. If usage and syntactic beahviour are used as classifactory features, Yoruba connective items can be classified into two broad categories: the first is the conjunction which is sub-classified into lexical/phrasal conjunction and sentence conjunction. The second one is disjunction which is subclassified into: bi-structural and uni-structural disjunctions.



OPEN ACCESS

**Keywords:** Conjunction, Grammatical item, Syntactic behaviour, Usage constraints, Yorùbá

## 1. Ìfáárà

Àwọn àpẹẹrẹ ìhun gbólóhùn tó wà ní (1a-d) ní ìsàlẹ̀ yìí, àwọn ọ̀rọ̀ kan wà tí a kọ́ níbùú àti ní àkọhàn oníbùú, a máa ń lò wọ́n gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ tí a fi ń so ọ̀rọ̀ tàbí ìhun méjì pọ̀ (Awobuluyi, 1978; Yusuf, 1999; Bamgbose, 1990; Yusuff, 2006 àti àwọn mìíràn).

1a) Ọlá ***àti/pẹ̀lú*** Fọlá jẹ́ ọ̀rẹ́

b) Òkùnrin dúdú náà ***àti/pẹ̀lú*** àwọn èèyàn rẹ̀ dúró de àlèjò pàtàkì

d) Ní ọla ***àti/pẹ̀lú*** ní ọ̀tunla ni aputupu ó hu

Àwọn ọ̀rọ̀ náà yàtọ̀ ní ìṣesí àti ìtumọ̀ wọn sí àwọn ọ̀wọ́ tí a rí nínú ti ìsàlẹ̀ wọ̀nyí:

2a) Tọlá fẹ́ràn ẹ̀gbọ́n rẹ̀ ***ṣùgbọ́n/àmọ́*** Lọlá fẹ́ràn àbúrò rẹ̀

b) Adé kúrú, ó ***sì*** sanra

Ohun tí àwọn onímọ̀ fi yé wa ní pé, àwọn ọ̀rọ̀ tí a kọ ní àkọhàn wọ̀nyí jẹ́ ọ̀rọ̀-àsopọ̀. Bẹ́ẹ̀ sì ni pé, ìṣesí àti ìhùwàsí wọn nínú ìhun kò jọra. Àwọn onímọ̀ kan gbà pé a lè so ọ̀wọ́ àwọn ọ̀rọ̀ kan pọ̀ láìlè so àwọn ọ̀rọ̀ mìíràn pọ̀ pẹ̀lú ọ̀rọ̀-asopọ̀. Bẹ́ẹ̀ sì ni pé a máa ń ka gbogbo àwọn ọ̀rọ̀ náà sí abẹ́ ìsọ̀rí kan náà. Púpọ̀ nínú àwọn onímọ̀ ni wọ́n ti ṣe akitiyan ní oríṣìíríṣìí láti sọ nípa àwọn ọ̀rọ̀-àsopọ̀ wọ̀nyí. Ṣùgbọ́n, nínú iṣẹ́ yìí, ohun tí ó jẹ àwa lógún gan-an ni láti ṣe àtúngbéyẹ̀wò àwọn ọ̀rọ̀-àsopọ̀ wọ̀nyí láti mọ ìlò wọn, ìṣesí wọn, ọ̀wọ́ tàbí ìpínsísọ̀rí tí a lè kà wọ́n sí àti láti ṣàpèjúwe wọn bó tí tọ́. Ìdí ni èyí tí a fi fẹ́ mọ ìdáhùnsí àwọn ìbéèrè iṣẹ́ ìwádìí yìí. A fẹ́ mọ bí ìṣesí, ìhùwàsí àwọn ọ̀rọ̀-àsopọ̀ ṣe rí ní èdè Yorùbá. Ṣé lóòtọ́ ni àwọn kan ṣeé pàarọ̀ ara wọn láìfa ìyàtọ̀ ìtumọ̀ ìhun náà? Ǹjẹ́ gbobo wọn ni wọ́n jẹ́ ọ̀rọ̀-àsopọ̀ tabí àwọn kan ní ìsọ̀rí mìíràn tó fara pẹ́ ti ọ̀rọ̀-àsopọ̀?

## 2. Iṣẹ́ àwọn ẹni ìṣáájú

Gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú iṣẹ́ àwọn onímọ̀, oríṣìíríṣìí ọ̀nà ni àwọn onímọ̀ gírámà ti gbà láti ṣàpèjúwe ọ̀rọ̀-àsopọ̀ àti láti ṣàtúnpín wọn sí ọ̀wọ̀ọ̀wọ́. Ní abala yìí, a ṣàgbéyẹ̀yò ìṣẹ́ àwọn ẹni ìṣáájú lórí ọ̀rọ̀-àsopọ̀ láti mọ ibi tí iṣẹ́ dé àti ibi tí iṣẹ́ kù sí.

Awóbùlúyì (1978) ki ọ̀rọ̀-àsopọ̀ gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ tí ó ń fi òye pé ọ̀rọ̀ méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ jọ lọ pọ̀ tàbí pé wọ́n ti di ọ̀kanhùn. Ìyẹn ni pé, ọ̀rọ̀-àsopọ̀ máa ń so ọ̀rọ̀ méjì tàbí àlòpọ̀-ọ̀rọ̀ pọ̀ tí yóò sì fi yéni pé ìtumọ̀ irú ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ jọ lọ pọ̀ tàbí pé wọ́n yóò jọ ní ìtumọ̀ kan náà. Ó ya irúfẹ́ àwọn ọ̀rọ̀ bí “àti”, “pẹ̀lú” sọ́tọ̀ gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀-àsopọ̀, ó sì fi ṣàlàyé pé wọ́n yàtọ̀ ní ìtumọ̀ àti òye sí ìbátan wọn ọ̀rọ̀ a-so-èjì-ọ̀rọ̀-pọ̀ tí a mọ̀ sí “disjunction” ní Gẹ̀ẹ́sì. Ìyẹn ni pé, wọ́n jọ ara wọn ní irúfẹ́ ìṣesí-gírámà tó dá lórí àyè wọn nínú ìhun, àti síso nǹkan pọ̀. Nítorí náà, Awobuluyi (1978) fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé, Yorùbá kò ní ọ̀rọ̀-àsopọ̀ fún gbólóhùn lẹ́yìn tí ó tọ́ka sí “sì” pé ó jẹ́ aláìfiwàjọ ọ̀rọ̀-àsopọ̀. Nítorí pé àwọn onímọ̀ ìṣáájú wòye pé, gbólóhùn ni ó máa ń wà ní iwájú àwọn ìhun náà ni wọ́n ṣe kà wọ́n sí ọ̀rọ̀-àsopọ̀ gbólóhùn. Wọ́n ń fi òye pé èrò méjì jẹ́ ojú-àti-òdì ara wọn. Ìyẹn ni pé, gbógbó wọn kì í ṣe ọ̀rọ̀-àsopọ̀. Bí a bá tẹ̀lé èrò Awóbùlúyì (1978) yìí, a lè pín àwọn ọ̀rọ̀ tó lè so ọ̀rọ̀ pọ̀ sí ọ̀wọ́ méjì nípa lílo àbùdá ìṣọwọ́so-ọ̀rọ̀-pọ̀ tàbí àbájáde ìtumọ̀ ìsopọ̀ náà: ọ̀rọ̀-àsopọ̀ àti ọ̀rọ̀-a-so-èjì-èrọ̀-pọ̀. Àmọ́ Awobùlúyì (1978) náà ni ó sọ pé àwọn elédè máa ń lo ọ̀rọ̀-àsopọ̀ lọ́pọ̀ ìgbà láti fi yálà ìbáṣepọ̀ tàbí ìṣòdìsí/ìyapa hàn. Awóbùlúyì (1978:106) tọ́ka àwọn wọ̀nyí: “àfi/àyàfi”, “àmọ́”, “ṣùgbọ́n”, “bóyá...àbí/tàbí”, “yálà...àbí/tàbí”, àti “aǹbọ̀ọ̀sí/aǹbọ̀torí/aǹbẹ̀lẹ̀ǹté/aǹbẹ̀lẹ̀tàsẹ̀”.

Yusuf (1980) náà tọ́ka sí èrò Stockwell et. al. (1973) pé elédè máa ń lo ọ̀rọ̀ àsopọ̀ láti fi ìbáṣepọ̀ ọ̀rọ̀ hàn. Irú ìbáṣepọ̀ náà lè jẹ́ ti ìjọra (similarity), ìjọṣẹlẹ̀ (simultaneity), ṣísẹ̀-n-tẹ̀lé (sequentiality), abbl.

Èyí fi hàn pé, irú ọ̀kanhùn ni wọ́n. Ọ̀kan lára iṣẹ́ tí ọ̀rọ̀-àsopọ̀ ń ṣe ní ó hàn nínú ọ̀rọ̀ a-so-èjì-èrò-pọ̀. Ṣùgbọ́n, wọ́n yàtọ̀ sí ọ̀rọ̀-àsopọ̀ gbólóhùn bíi ti "and" ní Gẹ̀ẹ́sì. Yusuf (198) náà tọ́ka sí àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ àsopọ̀ lédè Yorùbá: àti, pẹ̀lú, òun, àfi, àmọ́, ṣùgbọ́n, bóyá...àbí/tàbí, yálà...àbí/tàbí, áńbọ̀sí/bèlètàsé, síbẹ̀síbẹ̀, sì, bẹ́ẹ̀ ni. Bí a ṣe ń lo àwọn wúnrẹ̀n ìyísódì wọ̀nyí ni ó jẹ́ àwa lógún nínú iṣẹ́ yìí.

Yusuf (1999) ki ọ̀rọ̀ àsopọ̀ gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ ti a fi ń so àpólà ọ̀rọ̀ tàbí gbólóhùn pọ̀. Oríkì yìí jọ ti àfimọ̀ ti tíọ́rì gbé kalẹ̀ nítorí pé nínú tíọ́rì olófin ìyídà, ẹyọ ọ̀rọ̀ lè ṣiṣẹ́ gẹ́gẹ́ bí àpólà orúkọ. Àmọ́ irú àpólà àti gbólóhùn tó ṣeé so pọ̀ ni kò ṣàpẹẹrẹ rẹ̀ fún wa. Èrò rẹ̀ kò yàtọ̀ sí ti Yusuf (1980) tí a ti mẹ́nubà ní ìṣáájú.

Bámgbóṣé (1990: 189) ṣàlàyé pé "gbólóhùn alákànpọ̀ ni èyí tí a fi ọ̀rọ̀-àsopọ̀ so àwọn gbólóhùn mìíràn pọ̀ láti di ẹyọ kan". Àmọ́ ṣá, kì í ṣe gbogbo ohun tí a bá fi ọ̀rọ̀-àsopọ̀ so pọ̀ ni yóò ní ìtumọ̀ kan. Bẹ́ẹ̀ sì ni pé kìí ṣe gbólóhùn nìkan ni a lè fi ọ̀rọ̀-àsopọ̀ so pọ̀ nínú èdè Yorùbá. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé èrò yìí kò ki ọ̀rọ̀-àsopọ̀ gan-an, ó fún wa ní ìwòréré ìṣesí àwọn ọ̀rọ̀-àsopọ̀.

Ní ti Yusuff (2006: 37), ó ki ọ̀rọ̀-àsopọ̀ gẹ́gẹ́ "ọ̀rọ̀ tí ó ń so ọ̀rọ̀ pọ̀, so àpólà ọ̀rọ̀ pọ̀ tàbí so gbólóhùn pọ̀". Èyí dálé ọ̀kan lára ìhùwàsí ọ̀rọ̀-àsopọ̀ àti irúfẹ́ nǹkan tó lè so pọ̀, tíí ṣe ọ̀rọ̀, àpólà àti gbólòhùn. Bí a bá gùnlé oríkì ti Yusuff (2006) yìí, a ó kíyèsi pé kì í ṣe oríṣìí ọ̀rọ̀-àsopọ̀ kan ni ó wà látàri irúfẹ́ nǹkan tí wọ́n lè so pọ̀. Ó pín àwọn ọ̀rọ̀-àsopọ̀ sí ìsọ̀rí pẹ̀lú lílo àbùdá ìtumọ̀. Àwọn náà ni *ọ̀rọ̀-àsopọ̀ oníjọra*: àti/ti, pẹ̀lú, òun. Ohun tí ó jẹ wọ́n lógún ni irúfẹ́ ìjọra tó wà núnú ìhun tí àwọn wúnrẹ̀n àsopọ̀ náà so pọ̀. Ṣùgbọ́n, wọ́n kò mẹ́nubà á pé ìjọra yìí kì í ṣe ti irúfẹ́ àbùdá ọ̀rọ̀ tí ó ń so ìhun méjèèjì pọ̀. ìtumọ̀ ni wọ́n gùnlé. Àti pé, gbogbo bí elédè ṣe lè lo àwọn wúnrẹ̀n náà ni àlàyé kò jìnlẹ̀ tó lé lórí. Ó tilẹ̀ sọ pé àgékúrú "àti" ni "ti" jẹ́. Àti pé ìtumọ̀ àkànlò ni ó sáábà máa jẹ́. oríṣìríṣìí àríyànjiyàn ni ó wà lórí "tí" ní èdè Yorùbá bíi Awóbùlúyì (2008) àti àwọn mìíràn tí wọ́n ti mẹ́nuba ọ̀rọ̀ lórí rẹ̀.

Èkejì ni *ọ̀rọ̀-àsopọ̀ oníyapa:* "àyàfi/àfi", "àmọ́", "ṣùgbọ́n", "síbẹ̀", "bóyá...tàbí/àbí", "yálà...tàbí/àbí", "áńbọ̀sí/áńbèlètè/áńbọ̀sìbọ́sí". Àkópọ̀ wà nínú ọ̀wọ́ yìí. Bí a bá wo ìtumọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí àti irúfẹ́ bí elédè ṣe ń lò wọ́n, yóò fojú hànde pé àkópọ̀ lásán ni ó ṣẹlẹ̀ níbí. Bẹ́ẹ̀ sì ni ***síbẹ̀*** gba àkíyèsí. Ọ̀wọ́ kẹta ni *ọ̀rọ̀-àsopọ̀ onítẹ̀léǹtẹ̀lé* tíí ṣe ***sì***. Ó ka "òun" sí ọ̀rọ̀-àsopọ̀ lòdì sí èrò Ìlọ̀rí (2012) lóri "òun". Bí ó tilẹ̀ rí báyìí, àlàyé Yusuff (2006) fẹjú díẹ̀ ju gbogbo àwọn yóòkù lọ àmọ́ kò tẹpelẹmọ́ ìṣesí àti ìhùwàsí nínú ìhun láti fi bí wọ́n ṣe rí hàn. Iṣẹ́ tí a fẹ́ ṣe ni àtúngbéyẹ̀wò àti ìfẹ̀lójú àwọn iṣẹ́ tó ti wà nílẹ̀ àti láti tún mú èrò àti òye nípa àwọn ọ̀rọ̀-àsopọ̀ jinlẹ̀ si.

Ìlòrí (2010) ṣàgbèyẹ̀wò ọ̀rọ̀-àsopọ̀ Yorùbá. Ọ̀rọ̀ àpọ́nlé aṣáájú ìṣe ni ó pè "sì", tí "dẹ̀" jẹ́ ẹ̀dà rẹ̀. Àlàyé rẹ̀ dálé Tíọ́rì Oníwọ̀ba-Èròjà. Ó ní ìgbésíwájú ló fa kí ó máa jẹ yọ ní ibi tí ó ti ń jẹyọ. Ó gbà pé kò sí ọ̀rọ̀-àsopọ̀ tí ó dàbí "ṣùgbọ́n/àmọ́" tí a lè pè ní ọ̀rọ̀-a-so-gbólóhùn-pọ̀ nínú èdè Yorùbá ní ìbámu pẹ̀lú Awóbùlúyì (1978). Ìlọ̀ri (2012) wòye pé "òun" kì í ṣe ọ̀rọ̀-àsopọ̀ gẹ́gẹ́ bí ìmọ̀ àtijọ́ ti fi hàn wá. Iṣẹ́ rẹ̀ gan-an ni awẹ̀yìn tí ó ń tọ́ka sí ọ̀rọ̀-orúkọ ìṣáájú. A faramọ́ èrò yìí nítorí pé kò sé, kò yà sí "òun" tíi ṣe ọ̀rọ̀-arọ́pò orúkọ gígùn. Nítorí náà, "òun" kò sí lára àwọ́n ọ̀rọ̀-àsopọ̀ wọ̀nyí.

Abimbola (2015 ) ṣàgbéyẹ̀wò èrò àtijọ lórí ọ̀rọ̀-àsopọ̀. Ó dálé àríyànjiyàn tó wà lórí "sì", pé ṣé èdè Yorùbá ní ọ̀rọ̀-àsopọ̀ ti gbólóhùn àbí kò sí? Awóbùlúyì (1978) ti kọ̀kọ́ ṣe àlàyé pé kò sí. Ṣùgbọ́n púpọ̀ nínú àwọn onímọ̀ gírámà bí Yusuff (2006), Ilori (2010), Abimbola (2015) àti àwọn mìíràn ni wọ́n gbà pé "sì" jẹ́ ọ̀rọ̀-àsopọ̀. Èrò Abimbola (2015) ni pé, "sì" pé oríṣìí nínú èdè Yorùbá: *sì* atọ́ka ìtẹnumọ́, *sì* atọ́ka ìṣẹlẹ̀ ṣíṣẹ̀-n-tẹ̀lé, *sì* tíi ṣe ọ̀rọ̀-àsopọ̀. Yàtọ̀ sí àwọn mẹ́ta yìí, ó ní èdè Yorùbá ní ọ̀rọ̀-àsopọ̀ gbólóhùn oníríìsí afarasin nínú àwọn gbólóhùn tí "*sì*" ti ń ṣiṣẹ́ gẹ́gẹ́ bí ìtẹnumọ́ tàbí ìṣẹ̀lẹ̀ ṣíṣẹ̀-n-tẹ̀lé.

Adékẹ́yè (2016) náà kí ọ̀rọ̀ àsopọ̀ gẹ́gẹ́ bí wúnrẹ̀n tàbí ọ̀rọ̀ tí ó ń só ẹyọ ọ̀rọ̀, àpólà, tàbí odidi gbólóhùn pọ̀. Ṣùgbọ́n, èrò rẹ̀ kò yàtọ̀ sí àwọn àlàyé tó ti wà tẹ̀lẹ̀. Abimbola (2024) náà fi kun pé ọ̀rọ̀-àsopọ̀ náà jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ọ̀rọ̀ aṣegírámà tàbí wúnrẹ̀n aṣegírámà nítorí láìlò ó nínú ìhun a kò lè mọ

ohun tó túmọ̀ sí bí àwọn ọ̀rọ̀ bí ọ̀rọ̀-ìṣe, ọ̀rọ̀-orúkọ̀, àti àwọn mìíràn. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé a ti wo ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ àwọn oríkì kan tẹ́lẹ̀, kò sí èyí tó tọ́ka sí àbùdá kan tí ìsọ̀rí ọ̀rọ̀-àsopọ̀ ní bí ó ṣe hàn nínú oríkì yìí: ọ̀rọ̀-àsopọ̀ ni irúfẹ́ àwón ọ̀rọ̀ aṣegírámà tí wọ́n ń fi so ọ̀rọ̀, àpólà, gbólóhùn méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ pọ̀ láti fi wọ́n hàn pé wọ́n ṣe ọ̀kan ní èrò (Abimbola, 2024). Àbùdá kan tó ya ìsọ̀rí ọ̀rọ̀-aṣegírámà sọ́tọ̀ ni pé a kò lè ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ lára wọn tàbí kí a fi kún wọn nínú èdè bí a ti lè ṣe fún ọ̀rọ̀-orúkọ àti ìsọ̀rí àwọn ọ̀rọ̀ mìíràn. A kò lè fi kún ọ̀rọ̀-àsopọ̀ èdè Yorùbá, nítorí náà. A ó wo àwọn àbùdá tó sọ ọ̀rọ̀-àsopọ̀ di wúnrẹ̀n tàbí ìsọ̀rí ọ̀rọ̀-aṣegírámà.

### 3. Ọgbọ́n Ìṣèwádìí

A ṣe àmúlò àwọn fọ́nrán gbólóhùn tí ó ti wà nílẹ̀ tẹ́lẹ̀ nínú àwọn ìwé gírámà. A tún ṣàmúlò àwọn ìhun gbólóhùn tí a ti tò jọ fún àyẹ̀wò ní onírúurú fún àkojọ dáta wa. Èròǹgbà wa ni pé bí a bá lè ṣàpèjúwe wọn dáadáa, òye nípa wọn yóò túnbọ̀ jinlẹ̀ ju tàtẹ̀yìnwá lọ.

### 4. Ọ̀rọ̀-àsopọ̀ Yorùbá gẹ́gẹ́ bí wúnrẹ̀n aṣegúirámà

Gẹ́gẹ́ bí a ti mẹ́nu bà á lókè pé Abímbọ́lá (2024) tọ́ka pé ọ̀rọ̀-àsopọ̀ jẹ́ ọ̀wọ́ ìsọ̀rí aṣegírámà, wúnrẹ̀n aṣegírámà ni ọ̀wọ́ àwọn ọ̀rọ̀ tí wọ́n ní ìtumọ̀ gírámà (tàbí èyí tí kò ní ìtumọ̀ kankan), yàtọ̀ sí àwọn ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀ aláìnítumọ̀ gírámà tí wọ́n ní ìtumọ̀ kíkún tí a lè tètè mọ̀ (McIntyre, 2015:1). Ìyẹn ni pé láìmú wọn lò nínú ìhun gbólóhùn, kò ṣeé ṣe kí a lè tètè tọ́ka ìtumọ̀ tí àwọn wúnrẹ̀n aṣegírámà ní. Ó tọ́ka àwọn ọ̀rọ̀ bíi atọ́ka aṣàfihàn, ọ̀rọ̀-àsopọ̀, atọ́ka amúpé àti àwọn yòókù. Èyí fi hàn pé ọ̀rọ̀-àsopọ̀ jẹ́ ọ̀kan lára wọn bí a bá wo ìṣesí wọ́n ní ìbámu pẹ̀lú oríkì wúnrẹ̀n aṣegírámà òkè yìí. Bákan náà ni Rizzi àti Cinque (2016) sọ pé ìyàtọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ aṣegírámà àti ọ̀rọ̀ aláìṣegírámà yàtọ̀ sí níní ìtumọ̀ ajẹmọ́gírámà tí ó sábà máa ń jẹ mọ́ afòyemọ̀ ni pé, àwọn ọ̀rọ̀ tàbí wúnrẹ̀n aṣegírámà sábà máa ń ní:

- **i)** Ìhun/ìrísí fonọ̀lọ́jì tó yàtọ̀. Àwọn ọ̀rọ̀-àsopọ̀ èdè Yorùbá máa ń sábà bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú ìró kọ́ńsónáǹtì. Púpọ̀ nínú wọn ni wọ́n jẹ́ oní-sílébù méjì. Èdè Yorùbá ní ọ̀wọ́ àwọn tí wọ́n jẹ́ ẹlẹ́là bí a bá wo ìhun wọn tí abala ìhun tí wọ́n ń so pọ̀ yóò sì wà láàárín.
- **ii)** Iye tó ṣeé kà nínú èdè. A kì í lè fi kún iye wọn nínú èdè. Bí iye àwọn ọ̀rọ̀-àsopọ̀ ṣe rí ní èyí fi hàn. A kò lè fi kún iye wọn ní èdè Yorùbá.
- **iii)** Àìlèṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ tuntun láti ara wọ́n. Ó jẹ́ àbùdá pàtàkì tí ó tún fi wọ́n hàn gẹ́gẹ́ bí wúnrẹ̀n aṣegírámà nítorí a kò lè ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ lára wọn. "Àti/ti" ni a sábà máa ń lè kànpọ̀ pẹ̀lú ọ̀rọ̀-orúkọ ní èdè Yorùbá. yàtọ̀ sí èyí tí a tọ́ka yìí, ṣíṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ láti ara ọ̀rọ̀-àsopọ̀ Yorùbá kò ṣeé ṣe.
- **iv)** Wọn a máa ṣokùnfà gbígbé ọ̀rọ̀ síwájú nínú ìhun. Bí wọ́n bá ní àwọn àbùdá tó yẹ làti fi gbé ọ̀rọ̀ láti ibi kan sí ìbòmíràn, bíi ìtẹnumọ́, àsọdọ̀tọ̀, abbl, wọ́n á fa gbígbé ọ̀rọ̀ tàbí fọ́nrán-ìhun náà. Èyí ṣeé ṣe nígbà tí a bá tẹnumọ́ àpólà orúkọ alásopọ̀ ní èdè Yorùbá.
- **v)** Wọ́n máa ń fa ìyípadà tàbí ìyàtọ̀ ajẹmọ́-ẹka-èdè nínú ìhun gírámà. Ní ọ̀pọ̀ọ̀gbà ni ó jẹ pé ìyàtọ̀ ajẹmọ́hùn gíràmà máa ń wáyé tí ó sì jẹ́ pé àwọn wúnrẹ̀n aṣegírámà ni ó máa ń ṣokùnfà wọn. Kódà, wọ́n lè mú kí ẹka-èdè kan yàtọ̀ sí èkejì. Nínú àwọn ẹka-èdè Yorùbá kan ní a ti sábà máa ń bá àwọn ọ̀rọ̀ bíi "aǹbẹ̀lète", "aǹbèlètàsé", abbl. pàdé.

Bí a bá wo àwọn àbùdá wọ̀nyí, a ó rí pé òótọ́ ni pé ọ̀rọ̀-àsopọ̀ èdè Yorùbá jẹ́ ìsọ̀rí wúnrẹ̀n aṣegírámà. Àfijọ kan tí àwọn wúnrẹ̀n aṣegírámà ní pẹ̀lú àwọn ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀ aláìṣegírámà ni pé wọ́n jọ máa ń jẹ́ orí-ìhun. Ọ̀rọ̀-àsopọ̀ lè jẹ́ orí-ìhun alásopọ̀ nínú gírámà èdè Yorùbá. Àwọn onímọ̀ tíọ́rì bíi ti tíọ́rì Oníwọ̀nba Èròjà sábà máa ń tọ́ka sí èyí. Ó tilẹ̀ fẹ́ẹ̀ jẹ́ pé gbogbo ìhun ni ó ní wọ́nrẹ̀n aṣegírámà tó gàbà lé wúnrẹ̀n aláìṣegírámà ní ọ̀nà kan tàbí òmíràn. Àmọ́, iṣẹ́ ti wa kò ní nǹkan ṣe pẹ̀lú tíọ́rì kankan bí kò ṣe pé kí a ṣe àlàyé ìṣàpèjú bí a ṣe ń lò wọ́n.

**Àtúnpínsísọ̀rí ọ̀rọ̀-àsopọ̀**

Ní abala yìí, ohun tó jẹ́ wá lógún ni láti yànnàná àwọn ọ̀wọ́ tí a lè pín onírúurú àwọn ọ̀rọ̀ àsopọ̀ sí fún ìṣàpèjúwe wọn. Oríṣìí ọ̀nà ni a lè gbà pín àsopọ̀ Yorùbá. Bí a bá gùnlé ohun tí wọ́n ń so pọ̀ tàbí ìhun-ìsopọ̀ gẹ́gẹ́ bí òṣùwọ̀n tàbí **àbùdá ajẹmọ́hun** láti ṣàtúnpín wọ́n sí ọ̀wọ̀ọ̀wọ́, a lè pín wọn sí ọ̀wọ́ méjì:

i) ***Ọ̀rọ̀ a-so-ọ̀rọ̀-orúkọ/àpólà-pọ̀***: àwọn wọ̀nyí ni a ń lò láti fi so ẹyọ ọ̀rọ̀/ọ̀rọ̀ orúkọ, ọ̀rọ̀-arọ́pò orúkọ gígùn, àpólà orúkọ, àti àpólà atọ́kùn pọ̀. Èyí ni *ọ̀rọ̀-a-so-ọ̀rọ̀-orúkọ-pọ̀* tàbí *ọ̀rọ̀-a-so-àpólà-pọ̀*. A ṣe àpèjúwe rẹ̀ ní ìsàlẹ̀. Àpẹẹrẹ ni: "àti/ti" àti "pẹ̀lú".

ii) ***Ọ̀rọ̀ a-so-gbólóhùn-pọ̀***: gẹ́gẹ́ bí orúkọ rẹ̀, èyí ni àwọn ọ̀rọ̀-àsopọ̀ tí a ń lò láti fi so gbólóhùn pọ̀ nínú èdè Yorùbá. A ṣe àpèjúwe wọn ní ìsàlẹ̀. Àpẹẹrẹ ni: sì, àti ọ̀rọ̀-àsopọ̀ onírísí afarasin.

Bí a bá gùnlé **àbájáde ìsopọ̀, ìṣọwọ́so-ọ̀rọ̀-pọ̀ tàbí àbájáde ìtumọ̀ ìsopọ̀** gẹ́gẹ́ bí òṣùwọ̀n tàbí àbùdá, a lè pín àwọn ọ̀rọ̀ tó ń so ọ̀rọ̀ tàbí ìhun méjì pọ̀ sí ọ̀wọ́ méjì:

i) ***Ọ̀rọ̀-àsopọ̀*** (conjunction): Ọ̀rọ̀-àsopọ̀ ni àwọn wúnrẹ̀n aṣegírámà tí a ń lò fi so ọ̀rọ̀ méjì, àpólà tàbí gbólóhùn méjì pọ̀ láti fi hàn pé àbáyọrí ìtumọ̀ àti ìhun wọn ṣe ọ̀kan. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn wọ̀nyí ni wọ́n wà nínú èdè Yorùbá láti so ẹyọ ọ̀rọ̀ méjì, àpólà orúkọ, àpólà atọ́kùn àti gbólóhùn pọ̀.

ii) ***Ọ̀rọ̀ a-sojú-sòdì-pọ̀*** (disjunction): Ìbátan ọ̀rọ̀-àsopọ̀ ni ọ̀wọ́ kejì yìí jẹ́ sí ọ̀rọ̀-àsopọ̀. Àwọn wọ̀nyí kò tí ì ní àpèjúwe tí ó tọ́ bó ti yẹ nínú àwọn ìwé gírámà ju kí wọ́n máa pè wọ́n ní ọ̀rọ̀-àsopọ̀ lọ. Wọ́n máa ń dúró sáàárín ìhun méjì tí wọ́n ń so pọ̀ tàbí kí wọ́n dúró ní ìbẹ̀rẹ̀ abala ìhun tí a fẹ́ so pọ̀ tí awẹ́ kan yóò sì jẹ́ mọ̀ọ́n-nú látàrí ìmọ̀tẹ̀lẹ̀ tí àtolùgbọ́ àtolùsọ ti ní tẹ̀lẹ̀. A tún lè pè wọ́n ní àwọn ọ̀rọ̀ a-so-èjì-èrò-pọ̀ bí "ṣùgbọ́n", "àmọ́", "àfi/àyàfi".

Bí a bá wo **ìrísí** tàbí **mọfọ̀lọ̀jì** àwọn ọ̀rọ̀-àsopọ̀ àti ọ̀rọ̀ asojúsòdìpọ̀ gẹ́gẹ́ bí òṣùwọ̀n, a lè pín gbogbo wọn sí ọ̀wọ́ méta:

i) ***Ọ̀rọ̀-àsopọ̀ aláwẹ́-kan***: Àwọn wọ̀nyí ni ọ̀rọ̀-àsopọ̀ bí "àti/ti", "pẹ̀lú", "àmọ́", "sì" tí wọ́n ní awẹ́ kan ṣoṣo. Wọn kò ṣe é là sí méjì.

ii) ***Ọ̀rọ̀ asojúsòdìpọ̀ aláwẹ́-ìhun kan/alábala kan***: Àpẹẹrẹ àwọn ọ̀rọ̀ asojúsòdìpọ̀ aláwẹ́ kan ni "ṣùgbọ́n" àti "àmọ́", "aǹbọ̀sí/aǹbọ̀torí/aǹbèlètàsé/aǹbọ̀sìbọ́sí" àti "síbẹ̀síbẹ̀". Wọ́n sì máa ń dúró láàárín wúnrẹ̀n méjì tí wọ́n ń so pọ̀.

iii) ***Ọ̀rọ̀-àsopọ̀ aláwẹ́-méjì/alábala-méjì***: Àpẹẹrẹ àwọn wọ̀nyí ni: "yálà...tàbí/àbí", "bóyá...tàbí/àbí",

**Àbùdá ajẹmérò:** Bí a bá gùnlé èrò, a lè wò ó pé ṣe èrò náà ṣọ̀kan tàbí èrò náà jẹ́ alójú-lódì tàbí oníyíyan èrò kan péré. Bí a bá wo ìye èrò tó wà nínú ìhun tí a ní a lè pin sí:

i) ***Elérò aṣọ̀kan:*** Èrò kan péré ni àwọn wọ̀nyí ń ṣàfihàn.

ii) ***Elérò atakora tàbí alójúlódì:*** èrò méjì tí wọ́n jẹ́ òdì ara wọ́n ni àwọn wọ̀nyí ń ṣàfihàn

iii) ***Oníyíyan èrò kan:*** Àwọn wọ̀nyí jẹ mọ́ yíyan èrò kan péré nínú méjì tó wà nílẹ̀.

**Àbùdá ajẹmọ́-ìlò:** Èyí ni ọ̀nà tí a gbà lo àwọn ọ̀rọ̀-àsopọ̀ gẹ́gẹ́ ọ̀nà láti pín wọn sí ìsọ̀rí̀sọ̀rí. Bí a bá gùnlé àbùdá yìí, a lè pín sí

i) ***Oníyíyàn:*** O gbà pé kí a yan ọ̀kan nínú ohun tí ó wà nílẹ̀.

ii) ***Aláìgbayíyàn:*** Èyí kò fàyè gba yíyàn láàárín ohun méjì.

Ní abala tó kàn ni a ti ṣe àpèjúwe ìlò ìkọ̀ọ̀kan àwọn ọ̀rọ̀ àsopọ̀ àti ọ̀rọ̀ asojúsòdìpọ̀ láti lè fa òté tí ó de ìlò wọn yọ.

**Ọ̀rọ̀- A-so-ọ̀rọ̀-orúkọ-pọ̀ tàbí Ọ̀rọ̀-a-so-àpólà-pọ̀**

Èyí ni àwọn ọ̀rọ̀-àsopọ̀ tí wọ́n ń so ọ̀rọ̀-orúkọ, ọ̀rọ̀-arọ́pò orúkọ gígùn, àpólà orúkọ àti àpólà àtọ́kùn pọ̀. Ní àkọ́kọ́, bí a bá yọ ọwọ́ "òun" kúró nínú wọn, yóò ku méjì péré: "àti" àti "pẹ̀lú". Bí ó ti lẹ̀ jẹ́ pé ọ̀rọ̀ tàbí àpólà ni a fi ń so pọ̀, a kì í fi so ọ̀rọ̀-arọ́pọ̀-orúkọ kúkúrù, ọ̀rọ̀-ìṣe, àpólà ìṣe, ọ̀rọ̀-àpejúwe, ẹ̀yán, ẹ̀pọ́n àti àwọn wúnrẹ̀n aṣegíràmà pọ̀ ní èdè Yorùbá. Ọ̀wọ̀ yìí ni ìsọ̀rí àwọn ọ̀rọ̀-àsopọ̀ tàbí a-so-ọ̀rọ̀-pọ̀ tí wọ́n máa ń lò báyìí.

**i)** ***Ọ̀rọ̀-orúkọ + ọ̀rọ̀-orúkọ (OR+OR):*** A lè èyíkéyìí nínú àwọn ***àti*** àti ***pẹ̀lú*** láti fi so àwọn ọ̀rọ̀ orúkọ méjì pọ̀. A ṣàfihàn wọn ní ipò olùwà, àbọ̀-ọ̀rọ̀-ìṣe àti àbọ̀ ọ̀rọ̀-atọ́kùn ní ìhun oníbùú. Àpẹẹrẹ:

3a) *Bọ́lá* ***àti*** *Ọlá* ra ilé kan

b) Wọ́n rí *ọkọ* ***àti*** *aya* ní ibẹ̀

d) Olú ra bàtà fún *Ayọ̀* ***àti*** *Dàda*

4a) *Tọ́lá* ***pẹ̀lú*** *Lọ́lá* jẹ́ ọmọ gidi

b) Mo ní *Bàbá* ***pẹ̀lú*** *Ìyá*

d) Mo rà á fún *Tolú* ***àti*** *Ẹ̀rín*

ii) ***Ọ̀rọ̀-arọ́pò orúkọ gígùn + ọ̀rọ̀-arọ́opò-orúkọ gígùn (AROG +AROG):*** àwọn ọ̀rọ̀-àsopọ̀ wọ̀nyí tún lè ṣiṣẹ́ gẹ́gẹ́ bí àsopọ̀ fún ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ gígùn méjì. Gbogbo àwọn AROG yìí jẹ́ mẹ́fà. Àbùdá ẹni àti iye ni a lè fi dá wọ́n mọ̀ tí wọ́n fi farajọ àwọn ọ̀rọ̀-arọ́pò orúkọ kúkúrú. Ṣùgbọ́n, wọ́n yàtọ̀ sí AROG pẹ̀lú àbùdá ìtẹnumọ́ tíí ṣe apàlà wọn (Abimbola, 2019).

5a) Ẹ̀yin **àti** èmi ni a jẹ tẹ́tẹ́ náà

b) Wọ́n sọ̀rọ̀ nípa ìwọ **àti** èmi

d) Àwọn òṣèré náà yóò pidán fún ẹ̀yin **àti** àwa ní alẹ́

6a) Ẹ̀yin **pẹ̀lú** òun náà ni wọ́n sọ

b) Wọ́n kìlọ̀ fún àwọn **pẹ̀lú** àwa

d) Ó fẹ̀ bá èmi **pẹ̀lú** ẹyin ṣeré

iii) Ọ̀nà kẹ́ta tí a tún lè gbà lò wọ́n ni a lè pín sí méjì bí a ṣe fi hàn ní ìsàlẹ̀ yìí:

a) ***Ọ̀rọ̀-arọ́pò orúkọ gígùn + ọ̀rọ̀-orúkọ (AROG+OR):*** A lè lo àwọn ọ̀rọ-àsopọ̀ náà nípa síso ọ̀rọ̀-arọ́pọ̀-orúkọ gígùn pọ̀ mọ́ ọ̀rọ̀-orúkọ. Níbi tí AROG yóò ti ṣáájú tí ọ̀rọ̀-orúkọ yóò tẹ̀le. Àpẹẹrẹ;

7a) Àwa **àti/pẹ̀lú** Ayọ̀ san owó wa

b) Bàbá rí ẹ̀yin **àti/pẹ̀lú** Adé

d) Wọ́n sọ̀rọ̀ sí èmi **àti/pẹ̀lú** Olú

b) ***Ọ̀rọ̀-orúkọ + ọ̀rọ̀-arọ́pò orúkọ gígùn (OR+AROG):*** Yàtọ̀ sí fífi àti tàbí pẹ̀lú so ọ̀rọ̀ pọ̀ bí a ṣe rí lókè yìí, ọ̀rọ̀-orúkọ lè ṣáájú kí a sì so pọ̀ mọ́ ọ̀rọ̀-arọ́pọ̀-orúkọ gígùn.

8a) Adé **àti/pẹ̀lú** òun ní ó dára

b) Ṣé mo sọ̀rọ̀ burúkú sí Ṣọlá **àti** ìwọ ní àná

d) Ó rí Adé Àkànkẹ́ **àti/pẹ̀lú** èmi ní ìrònà

iv) ***Àpólà atọ̀kùn + àpólà atọ̀kùn (APAT +APAT):*** Yàtọ̀ sí àpólà orúkọ ní sísopọ̀, àpólà atọ́kùn méjì náà lè di síso pọ̀ pẹ̀lú lílo àti tàbí pẹ̀lú. Ọ̀rọ̀-àsopọ̀ náà yóò dúró sáárín àpólà atọ́kùn méjì náà. Àpẹẹrẹ;

9a) Wọ́n gbé orọ̀ ní àdúgbò wa *ní àná* ***àti/*pẹ̀lú*** *ní ìjẹta*

b) *Ní pàlàbà* ***àti/*pẹ̀lú*** *ní bọrọgidi* ní gbẹ́ àwọn igi náà

v) Ọ̀nà mìíràn tí a tún lè gbà lo ***àti*** àti ***pẹ̀lú*** ni kí a ka ọ̀rọ̀-orúkọ ní ọ̀wọ̀ọ̀wọ́ tí yóò wá jẹ́ pé èyí tó kẹ́yìn ni a o fi ọ̀rọ̀-àsopọ̀ náà sí níwájú. Àpẹẹrẹ;

11a) Mo ra ilá, ẹ̀gúsí, ata àti pọ̀nmọ́

b) Ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ ni ọ̀rọ̀-orúkọ, ọ̀rọ̀-ìṣe, ẹ̀yán, àti ìyísódì

d) Èmi, ìwọ, òun àti ẹ̀yin ni wọ́n dárúkọ

e) Bàbá, ìyá, ọmọ, ará, àti ojúlùmọ̀ wà ní gbàgede

ẹ) Bọ̀lá, tọ̀lá, Fọ̀lá àti èmi wà ní agbo náà.

g) Fọlá ra bàtà, aṣọ, àpò àti nǹkan ọ̀bẹ̀ mìíràn

Ọ̀wọ́ àwọn ìsọ̀rí tí a tò jọ sókè wọ̀nyí nìkan ni wọ́n ń so pọ̀. Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ní ìṣáájú, ọ̀rọ̀-ìṣe, ọ̀rọ̀-atọ́kùn, wúnrẹ̀n aṣáájú-ìṣe, ọ̀rọ̀-àpèjúwe, ẹ̀yán, wúnrẹ̀n ìyísódì, àti àwọn aṣegbólóhùn ni a kì í fi àwọn ọ̀rọ̀-àsopọ̀ méjèèjì wọ̀nyí so pọ̀.

Ní ti ìtumọ̀, àwọn méjèèjì ni wọ́n ń ṣàfihàn ìbáṣepọ̀ láàárín ọ̀rọ̀ méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ gẹ́gẹ́ bí ìṣesí ọ̀rọ̀-àsopọ̀. Ṣùgbọ́n ó dà bí pé "pẹ̀lú" kì í ṣe lò bi ti "àti" ní àwọn sàkánì kan náà. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ:

- A lè lo ***àti*** láti fún wa ní ìtumọ̀ onítẹnumọ́-ṣísẹ̀-n-tẹ̀lé. Ìyẹn ni pé, ìtẹnumọ́ máa ń farahàn ní ṣísẹ̀-n-tẹ̀lé. Ní irú ìlò yìí, àwọn elédè Yorùbá sábà máa ń kan ọ̀rọ̀-àsopọ̀ "àti" mọ́ ọ̀rọ̀-orúkọ. Gẹ́bẹ́ bí àpẹẹrẹ:

11a) Àtèní, àtọ̀la, àtọ̀jọ́ gbogbo ni elédùmarè yóò máa wà.

b) Àtàná, àtòní, àtọ̀la kò sí ìyàtọ̀.

d) Àtọkọ, àtaya ni wọ́n kó riyẹriyẹ lọ.

e) Àtitàná, àtitòní ni mo máa gbà lọ́wọ́ rẹ.

ẹ) Àtèmi, àtìwọ, àtòun ni a gbọ́dọ̀ ṣe ara-wa lọ́kan.

Ṣùgbọ́n kò dàbí pé a lè lo "pẹ̀lú" bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ bí àwọn gbólóhùn kòbẹ́gbẹ́mu ìsàlẹ̀ wọ̀nyí ti fi hàn.

12a) *pẹ̀lánàá, pẹ̀lónìí kò sí èyí tó ṣẹ̀yìn mi

b) ?pẹ̀lọ̀kọ pẹ̀láya náà dáa.

- A lè lo ***àti*** láti fi ìtumọ̀ alálòpọ̀ hàn tí "pẹ̀lú" kò sì ṣe é lò bẹ́ẹ̀. Àpẹẹrẹ:

13a) Àti arúgbó àti omidan ń kùlùbọ́ ìdí.

b) Àti ọkùnrin àti obìnrin ni wọ́n máa ń kópa nínú ọdún náà.

d) *Pẹ̀lú arúgbọ́ pẹ̀lú omidan ń kùlùbọ́ ìdí

- Ó dà bí pé "pẹ̀lú" ń ṣiṣẹ́ gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ atọ́kùn.

14a) Bàbá pẹ̀lú àwọn àbúrò rẹ̀ ni ọ̀rọ̀ kàn. Mo pẹ̀lú wọn nígbà tí wọ́n ń sọ̀rọ̀.

b) Wọ́n sọ̀rọ̀ kan pẹ̀lú bàbá náà nípa ọmọ náà.

d) Wọ́n rí ọmọ náà pẹ̀lú òkú àdìyẹ lẹ́gbẹ̀ẹ́ ọ̀nà.

- A sábà máa ń lo "àti" fún ìsọdorúkọ láti ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀-orúkọ tuntun. Ṣùgbọ́n kò dájú pé a lè lo "pẹ̀lú" bẹ́ẹ̀. Dípò bẹ́ẹ̀, a lè fi "pẹ̀lú" sí iwájú àwọn ọ̀rọ̀ tí a ṣẹ̀dá látara "àti".

15a) àtijẹ, àtimu, àtiná, àtilò

b) pẹ̀lú àtijẹ, pẹ̀lú àtiná, pẹ̀lú àtilò

b) *pẹ̀lújẹ,

- A lè lo ***àti*** pẹ̀lú ìsọdorúkọ tí a lo ***pé*** láti ṣẹ̀dá. ṣùgbọ́n kò dá pé a lè lo pẹ̀lú bi èyí láìfa pé kí olùgbọ́ máa rò pé aláìgbédè ni olùsọ. Gẹ́gẹ́ bí àpééré:

16a) àti pé o lọ, àti pé o ò lọ kò kàn mí
b) àti pé wọ́n rán àpò náà àti pé wọn ò rán, bí ó bá sọnù, ìwọ ni wọ́n ó mú.
d) àti pé o ò ní sí ń bẹ̀ kò da nǹkan kan.
e) *pẹ̀lú o lọ, pẹ̀lú o ò lọ kò kàn mí

Àkíyèsí kan tí ó wà nínú èyí ni pé, bí ẹni gbé gbólóhùn alápòólà orúkọ atakora méjì sẹ́gbẹ̀ẹ́ ara wọn ni ó rí. A lè lo awẹ́ kejì láfi awẹ́ àkọ́kọ́ sí iní ìhun náà, àmọ́ gbogbo awẹ́ kejì ni ó gbọ́dọ̀ jẹ́ ìhun ìyísódì.

- Àti ni a sáábà máa ń lò nínú ìkàlọ́wọ̀ọ̀wọ́ ọ̀rọ̀-orúkọ. Ìyẹn ni pé bí a bá ń dárúkọ ọ̀rọ̀-orúkọ ní ìkọ̀ọ̀kan, a lè lo "àti" láti fi so gbogbo wọn pọ̀. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ:

17a) Ìrẹsì, ẹyin, ata, àti ẹran
b) Àga, tábìlì, pẹ́pẹ́, àti igi

- A máa ń lo "àti" nínú ìhun awẹ́-ìsopọ̀ nínú àpólà orúkọ. Ìyẹn ni pé, mọ̀ọ́n-nú ni awẹ́ tàbí abala tí a gé kúrò yóò jẹ́ fún àtolùgbọ́ àtolùsọ.

18a) Àtèmi náà ni wọ́n ń sọ
b) Àti gbogbo ìlú ni wọ́n pẹ̀ sí ibi ayẹyẹ náà.
d) Àti àárè ni wọ́n yẹ sí.

Gbogbo àkíyèsí àti àpèjúwe yìí ni ó fi hàn pé kì í ṣe gbogbo ìgbà ni a lè lo "àti" àti "pẹ̀lú" gẹ́gẹ́ bí pàṣípààrọ̀ ara wọn tàbí kí a sọ pé gbogbo ìgbà kọ́ ni a lè lò wọ́n gẹ́gẹ́ bí àrọ̀-ọ̀rọ̀ fún ara wọn láìpàdánù ìtumọ̀ ìhun náà. Ṣùgbọ́n, "àti" ni a lè lò fàlàlàfalala bí ó ṣe wù wá.

***Tàbí***

"Tàbí" dàbí "ṣùgbọ́n/àmọ́" ni. Ohun tí ó yà á sọ́tọ̀ sí wọn ni pé kì í so èrò inú gbólóhùn pọ̀. Èyí tàbí ìyẹn ni ó máa ń fi hàn. Ìyẹn ni pé, ìlò rẹ̀ jọ "àti/pẹ̀lú", òun kàn ń fi ìlò yíyan ọ̀kan nínú ohun méjì tí ó lè jẹ́ ọ̀rọ̀-orúkọ, àpólà orúkọ, àpólà atọ́kùn, àti AROG tí ó bá dúró lááàrín wọn. Kì í ṣe pé òye sísopọ̀ gan-an ni tirẹ̀, tirẹ̀ ni pé èèyàn kò le è mú ohun méjì náà pọ̀ àfi ọ̀kan. Èyí ni pé "yan ìkan nínú ohun méjì náà" ni ìtumọ̀ rẹ̀. Àpẹẹrẹ:

19a) Ilé ***tàbí*** owó
b) Èyí ***tàbí*** ìyẹn
d) Ipò ***tàbí*** ọlá

20a) Ìwọ ***tàbí*** èmi
b) Àwa ***tàbí*** àwọn

21a) Bàbá àgbà ***tàbí*** ọkùnrin dúdú náà máa sọ̀rọ̀ lórí ọ̀rọ̀ náà.
b) Agbádá ńlá ***tàbí*** ẹsikí fẹ̀rẹ̀gẹ̀dẹ̀ ni mo máa wọ̀ wá.
d) Ọkọ̀ bọ̀gìnnì ***tàbí*** ọkọ̀ akérò
e) ìyá arúgbó ***tàbí*** ọmọbìnrin ọ̀pẹ̀lẹ́ngẹ́

22a) Ní àná ***tàbí*** ní òní

b) Ǹjẹ́ ìwé náà wà fún àwọn ọ̀dọ́ ***tàbí*** fún àwọn màjẹ̀sín?

d) Fi òògùn náà sí ojú ***tàbí*** sí imú

Ọ̀rọ̀ àsopọ̀ yìí náà ní àwọn òté tó de ìlò rẹ̀ nínu ìhun gírámà èdè Yorùbá.

- Òté àkọ́kọ́ ni ó níí ṣe pẹ̀lú ìtumọ̀ ohun tí àsopọ̀ yìí ń ṣe. Ìyẹn ni pé, ó ń ṣàfihàn ohun méjì tí kò ṣe é gbà pọ̀ tàbí tí kò ṣe é yàn pọ̀ lẹ́ẹ̀kan ṣoṣo. Ọ̀kan ni èèyàn gbọ́dọ̀ yàn nínú nǹkan méjèèjì náà tí ó pàtẹ rẹ̀.
- Bí ìṣesí àti ìtumọ̀ rẹ̀ ti jọ "ṣùgbọ́n/àmọ́" tó, kì í so gbólóhùn pọ̀. Ọ̀rọ̀-orúkọ, àpólà orúkọ tàbí àpólà atọ́kùn ni ó máa ń so pọ̀ bíi ti "àti/pẹ̀lú".
- Àárín ìhun méjì tí o ń só pọ̀ náà ni ó ti máa ń jẹ́ yọ.

**Ọ̀rọ̀ Asojúsòdìpọ̀**

Irúfẹ́ àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí ni a tún lè pè ní *ọ̀rọ̀ asèjì-èròpọ̀* (a-so-èjì-èrò-pọ̀) tí wọ́n máa ń fi èrò mejì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ sí ẹ̀gbẹ́ ara wọn ṣùgbọ́n tí èrò wọn lè má tèlé ara wọn tàbí kí wọ́n jẹ́ ojú àti òdì ara wọn.

***Àfi/àyàfi***

Èyí ni àwọn ọ̀rọ̀ tí a lè lò láti so èjì èrò pọ̀ ṣùgbọ́n tí ó jẹ́ pé èrò tàbí gbólóhùn kejì gan-an ni a ń retí pé kí ó ṣe tàbí kó fidí múlẹ̀ kí èrò inú tàkọ́kọ́ tó lè wáyé. Ìyẹn ni pé, dandan ni kí gbólóhùn kejì ó ṣelẹ̀ kí ti àkọ́kọ́ tó lè dúró. Gbólóhùn kejì ni èrèdí tàbí òté fún ìmúṣẹ́ gbólóhùn àkọ́kọ́ ní ibi tí a bá ti lo "àfi/àyàfi". Yàtọ̀ sí èyí, òdì ni gbólóhùn àkọ́kọ́ máa ń jẹ́ sí èkejì. Àpẹẹrẹ:

23a) Adébọ̀lá kò níí lọ ***àfi/àyàfi*** bí ó bá rí Tolú ọ̀rẹ́ rẹ̀

b) Kò ní tẹ̀lé ọ ***àfi/àyàfi*** bí ó bá rí ẹ̀gbọ́n rẹ̀.

d) Àwọn òṣìṣẹ́ kò ní padà sẹ́nu iṣẹ́ ***àfi/àyàfi*** bí ìjọba bá fún wa ní ẹ̀kúwó

e) Lọlá kò ṣetán láti rinsẹ̀ ***àfi/àyàfi*** bí Tọlá bá máa lọ.

A lè lo "àfi" ní ìbẹ̀rẹ̀ gbólóhùn láìsí gbólóhùn tí a so ó mọ́ ní ìbẹ̀rẹ̀ rẹ̀. Ṣùgbọ́n ó wọ́pọ̀ láti máa lo "àfi" báyìí dáadáa ju "àyàfi" lọ. Àmọ́, bí a bá lo "àyàfi" báyìí, yóò fún wa ní ìtumọ̀ ìtẹnumọ́ ju ti "àfi" lọ. Àpẹẹrẹ:

24a) ***àfi*** bí o bá fẹ́ jẹ ẹran tútù

b) ***àfi*** bí o bá fún mi ní owó mi. f.w.

d) ***àyàfi*** bí ó bá fún mi ní owó mi.

Àwọn òté tó de ìlò "àfi/àyàfi" tí a lè tọ́ka sí ni

- Òté àkọ́kọ́ tí ó de ìlò "àfi/àyàfi" ni pé, gbólóhùn àkọ́kọ́ gbọ́dọ̀ jẹ́ òdì ti èkejì tí ó wà nínú ìhun tí ọ̀rọ̀-àsopọ̀ náà ń so pọ̀.
- Òmíràn tún ni pé, gbólóhùn kejì ni èrèdí tàbí àtẹ̀gùn fún ìmúṣẹ́ ohun tí ti àkọ́kọ́ ń sọ. Ìyẹn ni pé láì sí gbólóhùn kejì, ìjóòtọ́ èrò ti àkọ́kọ́ kò ṣe é ṣe.
- Bákan náà, gbólóhùn kejì sábà máa ń bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú "bí nǹkan bá rí báyìí". Ìyẹn ni pé, "bí" jẹ́ atọ́ka ìṣẹ̀lẹ̀ tinú gbólóhùn kejì.

***Àmọ́*** àti ***Ṣùgbọ́n***

Àwọn wọ̀nyí ni *ọ̀rọ̀ a-so-èjì-èrò-pọ̀* tí ìlò wọn wọ́pọ̀ jù ní ìsọ̀rí yìí. Kódà, nítorí pé wọ́n máa ń jẹ yọ pẹ̀lú ìrísí wọn láàárín gbólóhùn méjì, àwọn méjèèjì ni àwọn onímọ̀ kan ń pè ní ọ̀rọ̀-àsopọ̀ gbólóhùn. A lè lò wọ́n ní pàṣípààrọ̀ láì ba ìtumọ̀ gbólóhùn wọn jẹ́. Èrò inú gbólóhùn àkọ́kọ́ máa ń jẹ́ òdì gbólóhùn kejì. Èrò méjì sábà máa ń jẹ́ alójúlódì tàbí aṣelòdì arawọn.

25a) Ayọ̀ ọ́ ti bímọ ***àmọ́*n** kò mọ orúkọ rẹ̀
b) Èmi náà fẹ́ sọ̀rọ̀ ***ṣùgbọ́n*** ojú ń tì mí
d) Erin lè jà ***ṣùgbọ́n*** ó mojú

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé òdì náà ni gbólóhùn kejì máa ń jẹ́ sí ti àkọ́kọ́, kò pan dandan kí a bá atọ́ka ìyísódì pàdé nínú èrò kejì kí ó tó lè jẹ́ òdì èrò sí ti àkọ́kọ́. A lè pa gbólóhùn àkọ́kọ́ jẹ, kí a sì gbé ìkejì jáde pẹ̀lú "àmọ́/ṣùgbọ́n" ní ìbẹ̀rẹ̀ rẹ̀. Mọ̀ọ́n-nú ni gbólóhùn àkọ́kọ́ sáábà máa ń jẹ́ fún olùsọ àti olùgbọ́ nínú ìtàkurọ̀sọ. Ní ìrú ìlò báyìí, bí ìgbà tí àròjinlẹ̀ ti wáyé lórí gbólóhùn mọ̀ọ́n-nú náà ni.

26a) ***Ṣùgbọ́n*** mo sọ fún
b) ***Ṣùgbọ́n*** ó tó bẹ́ẹ̀ o.

27a) ***Àmọ́***, ó ní láti jẹ́ pé wọ́n rí ọkùnrin náà mú ni.
b) ***Àmọ́*** ta ni yóò ṣe tí kò ní wí?

**Ọ̀rọ̀-àsopọ̀ Aláwẹ́-ìhun tàbí alábala méjì**

Àwọn wọ̀nyí tún yàtọ̀ nítorí ìhun méjì ni wọ́n ń sopọ̀ yàtọ̀ sí bóyá gbólóhùn tàbí àpólà. Méjì ni wọ́n a sì lè lò wọ́n ní ọ̀gangan ìlò kan náà. Àkọ́kọ́ ni "yálà..tàbí/àbí"; èkejì ni "bóyá...tàbí/àbí".

***Yálà...tàbí/àbí*** àti ***Bóyá....tàbí/àbí***

Gbólóhùn tàbí àpólà méjì náà ni àwọn wọ̀nyí máa ń dúró láti ṣàfihàn èrò tàbí méjì tí aṣàfọ̀tẹ́ pẹpẹ rẹ̀ fún olùgbọ́ rẹ̀ pé kò lè mú ju ọ̀kan lọ lẹ́ẹ̀kan ṣoṣo. Ìkan nínú méjèèjì ni èèyàn gbọ́dọ̀ mú. Abala tàbí aláwẹ́ ọ̀rọ̀-àsopọ̀ náà yóò bẹ̀rẹ̀ gbólóhùn, àpólà tabí ọ̀rọ̀ àkọ́kọ́ nígbà tí abala tàbí awẹ́ kejì yóò dúró ní ìbẹ̀rẹ̀ ìhun gbólóhùn, àpólà tàbí ọ̀rọ̀ kejì tí ó ń so pọ̀.

28a) ***Yálà*** Fọlá pẹ̀jí ***tàbí/àbí*** kò pẹ́jí, dandan ni kí dáná àárọ̀
b) ***Yálà*** akọ ***tàbí/àbí*** abo, mú ìkan fún mi
d) ***Yálà*** o lọ ***tàbí/àbí*** o ọ̀ lọ

29a) ***Bóyá*** ẹ ti gbọ́ ***tàbí/àbí*** ẹ kò tîì gbọ́ pé àgan máa bẹ́
b) ***Bóyá*** akọ ***tàbí/àbí*** abo, n ó mú kan
d) ***Bóyá*** orí ni ***tàbí/àbí*** ìrù, kò kàn mí

Ìlò kan tó ya èyí sọ́tọ̀ ni pé ***àbí*** níkan ni ó lè bẹ̀rẹ̀ gbólóhùn tàbí abala kejì láìsí abala àkọ́kọ́ nínú ìhun náà. Ní ìrú ìlò yìí, gbólóhùn ìbéèrè ni ó máa ń yọrí sí.

| | | | | |
|---|---|---|---|---|
| 30a) | ***àbí*** mo ti pẹ́? | f.w. | 31a) | *tàbí mo ti pẹ́? |
| b) | ***àbí*** ẹ ò fún un mọ́ ni? | | b) | *tàbí ẹ ò fún un mọ́ ni? |
| d) | ***àbí*** kò tîì gbó? | | d) | ?tàbí kò tîì gbó? |

Àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí sún mọ́ra pẹ̀kípẹ̀kí ṣùgbọ́n, ìyàtọ̀ ìtumọ̀ díẹ̀ wà nínú ìlò wọn. ***Bóyá*** ń ṣàfihàn ohun tí èrò rẹ̀ kò tîì dájú. ***Yálà*** kò ṣe é lò bí a ṣe lè lo ***bóyá***. Ohun tí ***yálà*** túmọ̀ sí ni pé kí a mú ọ̀kan nínú méjèèjì.

32) ***Bóyá*** ní ọ̀la ni lílọ mi ó yá

Àsọlé gbólóhùn òkè yìí yóò sì jẹ́:

33) N kò mọ̀, tàbí
b) Kò yé mi.

Àwọn òté tó de ìlò àwọn ọ̀rọ̀ àsopọ̀ aláwẹ́-ìhùn tàbí alábala mẹ́jì náà

- Òté tó de ìlò ***yálà...tàbí/àbí*** àti ***bóyá...tàbí/àbí*** náà ni pé, ìhun ni ó máa ń so pọ̀. Ìhun gbólóhùn, ìhun àpólà tàbí ìhun ẹyọ ọ̀rọ̀ ni a lè lò ó fún.
- Apákan rẹ̀ yóò bẹ̀rẹ̀ abala ìhun àkọ́kọ́, apá kejì yóò sì bẹ̀rẹ̀ ìhun kejì.
- A lè pa abala ìhun àkọ́kọ́ àti abala ìbẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ àsopọ̀ náà jẹ́, kí ó jẹ́ mọ̀-ọ́n-nú tí awẹ́ yóò yóò sì jẹ́ a ṣeé gbà.

**Ọ̀rọ̀-àsopọ̀ aláwẹ́-kan/alábala-kan**

Èyí ni àwọn ọ̀rọ̀-àsopọ̀ tí wọ́n máa ń já ìrẹ̀tí ẹni nínú ìhun kejì tako ohun tí èèyàn ní lérò ní ìbẹ̀rẹ̀ ìhùn àkọ́kọ́. Àwọn ọ̀rọ̀-àsopọ̀ náà ni "ańbọ̀sí", "ańbọ̀sìbọ́sí", "ańbèlètàsé", "ańbèlèté" tí ìtumọ̀ àti ìhun wọn. Ọ̀kanhùn bẹ́ẹ̀ sì ni

34a) Kò ní owó lọ́wọ́ ***ańbọ̀ọ̀sí/ańbọ̀ìbọ́sí/ańbèlètàsé/ańbèlètè*** aṣọ ẹbí.

b) N kò ní ará ***ańbọ̀sí/ańbọ̀ìbọ́sí/ańbèlètàsé/ańbèlètè*** ẹni tí yóò gbé mi sínú adágún omi.

d) A kò lè lọ ***ańbọ̀sí/ańbọ̀ìbọ́sí/ańbèlètàsé/ańbèlètè*** kí a wá dá ẹmu bọ̀.

e) Bàbá kò rí ajá rẹ̀ ní ilé ***ańbọ̀sí/ańbọ̀ìbọ́sí/ańbèlètàsé/ańbèlètè*** alágbàro tó sùn fọnfọn sóko.

Àkíyèsí ìlò àwọn ọ̀rọ̀-àsopọ̀ wọ̀nyí fi hàn pé láàárín ọ̀rọ̀-orúkọ méjì tàbí àpólà orúkọ méjì ni a ti máa ń rí wọn nínú gbólóhùn kan. Ní apá kejì ọ̀rọ̀-àsopọ̀ yìí ni a tún lè rí ìsọ̀ọdorúkọ tàbí awẹ́-gbólóhùn aṣàpèjúwe. Ṣùgbọ́n ìhun àkiyèsí alátẹnumọ́ kò ṣeẹ lò bẹ́ẹ̀.

35a) N kò rí àpò-ìwé mi ***ańbèlètàsé*** *ìwé tí mo rà*

b) *n kò rí àpò-ìwé mi ***ańbèlètàsé*** *ìwé ni mo rà*

Yàtọ̀ sí èyí, gbólóhùn àkọ́kọ́ sábà máa ń jẹ́ gbólóhùn ìyísódì nítorí atọ́ka ìyísódì "kò" tí ó máa ń wà nínú rẹ̀.

Ohun mìíràn tún ni pé, a lè lo dípò ní àyè àwọn ọ̀rọ̀-àsopọ̀ wọ̀nyí.

36) Bàbá kò rí ajá rẹ̀ nílè ***dípò*** alágbàro tó sùn sóko.

Ohun kan tí ó tún dàbí ẹni pé ó máa ń farahàn nínú irúfẹ́ ìhun tí a lo àwọn ọ̀rọ̀-àsopọ̀ yìí so pọ̀ ni pé bí ìgbà tí èèyàn fi ìmọ̀lára ìfojútẹnimẹ́rẹ̀ tàbí ìfojútẹ -nǹkan-mẹ́rẹ̀ ni àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí ń ṣe. Pé a kò tíì sọ tí lágbájá tó sàn kí a tó máa mẹ́nuba tàmàdò tí kò jámọ́ nǹkankan.

**Ọ̀rọ̀-àsopọ̀ a-so-gbólóhùn-pọ̀ ajájogún**

Ohun kan tí a mọ̀ mọ àwọn ọ̀rọ̀ àsogbólóhùnpọ̀ wọ̀nyí ni pé, èrò inú gbólóhùn àkọ́kọ́ àti èkejì a máa gún tàbí pé a máa ṣọ̀kan gẹ́gẹ́ bí àbáyọrísí síso àpólà orúkọ tàbí ọ̀rọ̀-orúkọ pọ̀. Bẹ́ẹ̀ gẹ̀lẹ́ ni nǹkan rí pẹ̀lú ti gbólóhùn náà. Ìyàtọ̀ yìí gan-an ni ó ya ọ̀wọ́ yìí sọ́tọ̀ sí àwọn ọ̀rọ̀ a-so-èjì-èrò-pọ̀ tí a ti mẹ́nubà lókè. Àmọ́, gẹ́gẹ́ bí Abímbọ̀lá (2015) ti tọ́ka si í, kì í ṣe ọ̀rọ̀-àsopọ̀ kan ni ó wà. Arẹmu & Weisser (2024) náà tún tẹpẹlẹmọ mọ́-ọn pé "sì" jẹ́ ọ̀rọ̀-àsopọ̀.

***Sì: ọ̀rọ̀-asogbólóhùnpọ̀***

Ọlọ́tọ̀ ní tòun ọ̀tọ̀ ni ọ̀rọ̀ "sì" jẹ́ láàárín gbógbo ọ̀rọ̀ àsopọ̀ Yorùbá. Ohun kan tí a mọ̀ mọ àwọn ọ̀rọ̀-àsopọ̀ ni pé ní àárín ọ̀rọ̀ mẹ́jì tí wọ́n ń so pọ̀ ni wọ́n ti máa ń jẹyọ gẹ́gẹ́ àwọn tí a ti ṣàfihàn wọn ní ìṣáájú nínú iṣẹ́ yìí. ṣùgbọ́n sì tíì ṣe ọ̀rọ̀ asogbólóhùnpọ̀ yàtọ̀ ní ìhùwàsí nínú ìhun ní tirẹ̀. Kì í dúró sí àárín gbólóhùn méjì tí ó ń so pọ̀. Gẹ́gẹ́ Awóbùluyi (2022) ti sọ, ẹ̀yìn ó, ìyẹn sílébù olóhùn okè nínú

gbólóhùn kejì ni ó ti máa ń jẹ yọ. Bákan náà ni ọ̀rọ̀ jọra wọ́n nígbà tí Aremu àti Weisser (2024) náà sọ pé lẹ́yìn ìhun àlà-fonọ̀lọ́jì olùwà nínú gbólóhùn kejì ni ó ti máa ń jẹ yọ. Ohun kan tó ṣe kókó ni pé ibi ìdúrósí rẹ̀ kì í ṣe àárín ìhun méjì tó ń so pọ̀. Àpẹẹrẹ:

36a) Olú ga, ó ***sì*** tóbi

b) Ọkùnrin náà ṣàìsàn, ó ***sì*** kú

d) Bàbá àgbà sáré, kò ***sì*** sinmi

Lára àwọn òté tàbí ìṣesí tí a lè rí fàyọ nípa ***sì*** nínú gbólóhùn ni pé:

- ***Sì*** kì í jẹ yọ ní ipọ̀ tó wà láàárín gbólóhùn méjì tí ó ń so pọ̀, nínú gbólóhùn kèjì, lẹ́yìn ó tí ó máa ń jẹ yọ lẹ́yìn olùwà ni ó máa ń wà.
- Ìpò ìjẹyọ yìí náà ni òté àkọ́kọ́ tí ó de ìlò ***sì*** nínú gbólóhùn èdè Yorùbá.
- Òté mìíràn ni pé gbólóhùn ni a lè fi so pọ̀. A kò lè lo ***sì*** láti fi so ọ̀rọ̀-orúkọ, àpólà orúkọ, àpólà atọ́kùn tàbí èyíkẹ́yìí nínú ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ ní èdè Yorùbá.
- Òhun kan tí ìlò ***sì*** tún máa ń mú dáni ni pé, àwọn gbólóhùn méjèèjì tí a so pọ̀ máa ń jẹ́ ajogún. Ìyẹn ni pé ìtumọ̀ kì í tako ara wọn tàbí pé wọn kì í ṣe onítumọ̀ ojú àti òdì.

***Ọ̀rọ̀-asogbólóhùnpọ̀ anírísí afarasin***

Gẹ́gẹ́ bí Abimbola (2015) ti sọ, àwọn gbólóhùn kan tí a ti rí ***sì*** ṣùgbọ́n tí kì í ṣe ọ̀rọ̀-àsopọ̀ ni níbẹ̀. Ìyẹn ni pé, ìtumọ̀ ìṣẹ̀lẹ̀ ṣísẹ̀-n-tẹ̀lé àti ìtumọ̀ ìtẹnumọ̀ ni àwọn ***sì*** náà ń tọ́ka. Wọ́n jẹ́ ọ̀rọ̀ afirísíjọra ṣùgbọ́n ìtumọ̀ wọn yàtọ̀ sí ti ọ̀rọ̀-àsogbólóhùnpọ̀ tí ó kàn iṣẹ́ yìí. Bí ọ̀rọ̀ ti rí yìí, ohun kan wà tí ó ń ṣiṣẹ́ àsopọ̀ bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé a kò mọ ìrísí rẹ̀ tàbí pé ìrísí àdámọ́ rẹ̀ jẹ́ àìfojúrí. Nínú àwọn gbólóhùn bẹ́ẹ̀, ọ̀rọ̀-àsogbólóhùnpọ̀ ibẹ̀ náà ni èyí tí ìrísí rẹ̀ farasin. Àbùdá àdání tirẹ̀ ni pé kò ní ìrísí kankan tí a lè fi dáa mọ̀ gẹ́gẹ́ bí àwọn ìyókù tí a ti sọ nípa wọn lókè. Àpẹẹrẹ:

37a) Ó sì ṣe, mo sì sùn lái dijú

b) Olú sì dìde, ó dẹ ìgbẹ́, ó sì pa ẹran kan

Òté tó de ìlò ọ̀rọ̀-àsogbólóhùnpọ̀ yìí ni pé nínú àwọn gbólóhùn tí a ti rí àwọn sì méjì kan tí àkọ́kọ́ ń tọ́ka ìtumọ̀ ìtẹnumọ́, tí èkejì sì ń tọ́ka ìṣẹ̀lẹ̀ ṣísẹ̀-n-tẹ̀lé ni a ti lè lo ọ̀rọ̀-asogbólóhùnpọ̀ náà. Nítorí kò ṣe é ṣe fún ***sì*** tíí ṣe wúnrẹ̀n aṣáájú-ìṣe láti tún jẹ́ ọ̀rọ̀-asogbólóhùnpọ̀ láì fa ìrújú.

Ohun tí a ti ń gbájúmọ́ náà ni ìlò àti ìṣesí àwọn ọ̀rọ̀ asọ̀rọ̀pọ̀, asogbólóhùnpọ̀ tàbí asèròpọ̀. A tẹpẹlẹ mọ́ ọn pé oríṣìíríṣìí ni àwọn wúnrẹ̀ àsopọ̀ wọ̀nyí nínú èdè Yorùbá. Bákán náà ni a tẹnumọ́ àwọn òté fún ìlò wọn.

**5. Ẹ̀kọ́ fún àmúlò**

Wúnrẹ̀n aṣegírámà àwọn ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ méjèèjì jẹ́ ní èdè Yorùbá. nítorí, gbogbo àwọn ọ̀rọ̀ abẹ́ ìsọ̀rí yìí ni a kò lè fi ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ tuntun, a kò lè fi kún iye wọn, bẹ́ẹ̀ ni pé wọ́n ní ìtumọ̀ gírámà tí a lè fi dá waọn mọ̀. Ninú àpèjúwe ìlò àti ìṣesí àwọn ọ̀rọ̀-àsopọ̀ nínú èdè Yorùbá iṣẹ́ yìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé:

i) Kì í ṣe gbogbo àwọn ọ̀rọ̀ tí ìmọ̀ àtijọ́ ti kà sí ọ̀rọ̀ àsopọ̀ nínú gírámà èdè Yorùbá kó ni ó rí bẹ́ẹ̀. Nínú iṣẹ́ yìí, a sọ pé bí a bá gùnlé ìlò àti ìṣesí àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí, a lè pín wọn sí ọ̀wọ́ méjì: i) ọ̀rọ̀-àsopọ̀ àti ii) ọ̀rọ̀-a-so-èjì-èrò-pọ̀ tàbí ọ̀rọ̀-asojú-sòdì-pọ̀/elérò ajárètí.

ii) A ṣàmúlò àbùdá mẹ́rin láti pín àwọn ọ̀rọ̀ ìsọ̀rí yìí bí ó ti yẹ. 1) àbùdá ajẹmọ́hun. Méjì ni a pín wọ́n sí: *Ọ̀rọ̀ a-so-ọ̀rọ̀-orúkọ/àpólà-pọ̀* àti *Ọ̀rọ̀ a-so-gbólóhùn-pọ̀*; 2) Àbùdá àbájáde ìsopọ̀, ìṣọwọ́so-ọ̀rọ̀-pọ̀ tàbí àbájáde ìtumọ̀ ìsopọ̀ fún *Ọ̀rọ̀-àsopọ̀* (conjunction) àti *Ọ̀rọ̀ a-sojú-sòdì-pọ̀* (disjunction). 3) Àbùdá ìrísí tàbí mọfọ́lọ́jì àwọn ọ̀rọ̀-àsopọ̀ àti ọ̀rọ̀ asojúsòdìpọ̀: *Ọ̀rọ̀-àsopọ̀ aláwẹ́-kan*: ("àti/ti", "pẹ̀lú", "àmọ́", "sì"), *Ọ̀rọ̀ asojúsòdìpọ̀ aláwẹ́-ìhun kan/alábala kan*: "ṣùgbọ́n" àti "àmọ́", "ańbọ̀sí/ańbọ̀torí/ańbèlètàsé/ańbọ̀sìbọ́sí" àti "síbẹ̀síbẹ̀") àti *Ọ̀rọ̀-àsopọ̀ aláwẹ́-méjì/alábala-méjì* ("yálà...tàbí/àbí", "bóyá...tàbí/àbí") Àbùdá ajẹmérò**:** *Elérò aṣọ̀kan: Elérò atakora tàbí alójúlódì: Oníyíyan èrò kan:* 4) Àbùdá ajẹmọ́-ìlò: *Oníyíyàn* àti *Aláìgbayíyàn.*

iii) Nínú ìṣàpèjúwe ìkọ̀ọ̀kan àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí, a ṣàkíyèsí pé "àti/ti" àti "pẹ̀lú" ni a sáábà máa ń lò jù nínú àwọn *Ọ̀rọ̀ a-so-ọ̀rọ̀-orúkọ/àpólà-pọ̀* láti so ọ̀rọ̀ orúkọ méjì pọ̀, ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ gígùn, àpólà orúkọ àti àpólà atọ́kùn. A lè lo ***àti*** láti fún wa ní ìtumọ̀ onítẹnumọ́-ṣísẹ̀-n-tẹ̀lé. A lè lo ***àti*** láti fi ìtumọ̀ alálòpọ̀ hàn tí "pẹ̀lú" kò sì ṣe é lò bẹ́ẹ̀. y[atA sábà máa ń lo "àti" fún ìsọdorúkọ láti ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀-orúkọ tuntun. A lè lo ***àti*** pẹ̀lú ìsọdorúkọ tí a lo ***pé*** láti ṣẹ̀dá. Àti ni a sáábà máa ń lò nínú ìkàlọ́wọ̀ọ̀wọ́ ọ̀rọ̀-orúkọ. A máa ń lo "àti" nínú ìhun awẹ́-ìsopọ̀ nínú àpólà orúkọ. Ìyẹn ni pé, mọ̀ọ́n-nú ni awẹ́ tàbí abala tí a gé kúrò yóò jẹ́ fún àtolùgbọ́ àtolùsọ.

iv) "Tàbí" dàbí "ṣùgbọ́n/àmọ́" nítorí pé ó máa ń fi ìlò yíyan ọ̀kan nínú ohun méjì tí ó lè jẹ́ ọ̀rọ̀-orúkọ, àpólà orúkọ, àpólà atọ́kùn, àti AROG hàn. Kò ní òye sísopọ̀ gan-an ni tirẹ̀. òté ìlò rẹ̀ níí ṣe pẹ̀lú ìtumọ̀ ohun tí àsopọ̀ yìí ń ṣe. Ìyẹn ni pé, ó ń ṣàfihàn ohun méjì tí kò ṣe é gbà pọ̀ tàbí tí kò ṣe é yàn pọ̀ lẹ́ẹ̀kan ṣoṣo. ***Àfi/àyàfi*** ni àwọn ọ̀rọ̀ tí a lè lò láti so èjì èrò pọ̀ ṣùgbọ́n tí ó jẹ́ pé èrò tàbí gbólóhùn kejì gan-an ni a ń retí pé kí ó ṣe tàbí kó fidí múlẹ̀ kí èrò inú tàkọ́kọ́ tó lè wáyé. A lè lo "àfi" ní ìbẹ̀rẹ̀ gbólóhùn láìsí gbólóhùn tí a so ó mọ́ ní ìbẹ̀rẹ̀ rẹ̀. Ṣùgbọ́n a ò lè lo ***àyàfi*** bẹ́ẹ̀.

v) "Àmọ́ " àti "Ṣùgbọ́n" jẹ́ *ọ̀rọ̀ a-so-èjì-èrò-pọ̀* tí ìlò wọn wọ́pọ̀ jù ní ìsọ̀rí yìí. Wọ́n lè ṣe pàṣípààrọ̀ láìba ìtumọ̀ gbólóhùn wọn jẹ́. Èrò inú gbólóhùn àkọ́kọ́ máa ń jẹ́ òdì gbólóhùn kejì. Èrò méjì sábà máa ń jẹ́ alójúlódì tàbí aṣelòdì arawọn. Yàtọ̀ sí ìwọ̀nyí, "yálà...tàbí/àbí" náà ń ṣàfihàn yíyan èrò kan nínú gbólóhùn méjì náà. Ní ti "bóyá....tàbí/àbí", àfihàn ohun tí èrò rẹ̀ kò tîì dájú ni ìtumọ̀ rẹ̀. A jábọ̀ rẹ̀ nínú iṣẹ́ yìí pé "ańbọ̀sí", "ańbọ̀sìbọ́sí", "ańbèlètàsé", "ańbèlèté" jẹ́ ajárẹ̀tí ẹni nínú ìhun kejì tako ohun tí èèyàn ní lérò ní ìbẹ̀rẹ̀. A tún fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé "sì" jẹ́ ọ̀rọ̀ asogbólóhùnpọ̀ ní ìbámu pẹ̀lú èrò Abimbola (2015). Àti pé, ọ̀rọ̀ asogbólóhùnpọ̀ onírísí afarin náà wà. Ó máa ń jẹ yọ nínú àwọn ìhun gbólòhùn tí ó ní sì tí ó ń ṣiṣẹ́ ìtẹnumọ́ àti ìṣẹ̀lẹ̀ ṣísẹ̀-n-tẹ̀lé.

## 6. Àtúnbọ̀tán iṣẹ́-ìwádìí

Àwọn ẹ̀kọ́ tí a rí fàyọ nínú iṣẹ́ yìí yóò mú kí àyípadà dé bá ojú tí àwọn onímọ̀ fi ń wo ìsọ̀rí ọ̀rọ̀-àsopọ̀ (conjunctions) àti ọ̀rọ̀-a-sojú-sòdì-pọ̀ (disjunctions) yálà nínú ìhun àpólà tàbí nínú ìhun gbólóhùn. Ìtumọ̀ tí wọ́n ń fi kún ihun tí wọ́n bá ti jẹ yọ máa ń ṣe pàtàkì fún ìlòye kíkún bí ó ti yẹ.

## 7. Àgbálọgbábọ̀

Òótọ́ ni pé èdè Yorùbá dàbí ọ̀pọ̀lọpọ̀ èdè ọmọ̀nìyàn kárí ayé nipa irúfẹ́ ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀ tí ó ní. Lára àwọn ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀ tí ó ní náà ni ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀ aṣegírámà ọ̀rọ̀-àsopọ̀ wà. Ohun tí a kíyèsí ni pé yàtọ̀ sí bí àwọn onímọ̀ kan tí jẹ́ kí a mọ̀ tẹ̀lẹ̀, èdè náà ní orísìírísìí ọ̀rọ̀ tí a lè lò gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀-àsopọ̀. Nínú iṣẹ́ yìí, a ti ṣàlàyé àbùdá ọ̀rọ̀-àsopọ̀ èdè Yorùbá gẹ́gẹ́ ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀ aṣegírámà. Bákan náà ni a gbìyànjú láti ṣe àtúnpínsísọ̀rí lọ̀lọ̀kan-

ò-jọ̀kan àwọn ọ̀rọ̀-àsopọ̀ tí ó wà nínú èdè náà. Àbùdá mẹ́fà ni a lò láti pín ọ̀rọ̀ tó ń so ọ̀rọ̀ méjì pọ̀ ni èdè Yorùbá. Bí a ti ni ọ̀rọ̀-àsopọ̀ ni a ní ìbátán wọn tó jẹ́ pé èjì-èrò ni wọ́n ń so pọ̀. Bí a tin í ọ̀rọ̀-àsopọ̀ fún ẹyọ ọ̀rọ̀, àpólà orúkọ àti àpólà atọ́kùn, bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ náà ni a ní fún gbólóhùn. A ní àwọn ọ̀rọ̀ aláwẹ́-kan àti aláwẹ́-méjì. Yàtọ̀ sí gbogbo ohun tó níí ṣe pllú ìsọ̀rí, a ṣe àfàyọ àwọn òté tó de ìlò ìkọ̀ọ̀kan àwọn ọ̀rọ̀ náà.

**8. Ìmọríri**

Mo dúpẹ́ púpọ̀ lọ́wọ́ àwọn tí wọ́n ṣe ìgbéléwọ̀n àti àyẹ̀wò ìṣẹ́ yìí. Gbogbo àwọn àríwísí àti àtúnṣe wọn ni ó mú iṣẹ́ yìí dára sí i. Gbogbo àwọn tí wọ́n péjúpésẹ̀ sí ibi àpérò tí a ti kọ́kọ́ ka iṣẹ́ yìí ni 2024 National Conference of the Yoruba Studies Association of Nigeria (YSAN) náà ni a kí pé wọ́n ṣeun fún àwọn àkíyèsí, àtúntò àti àríwísí wọn. Mo dúpẹ́. Mo mọ rírì yín.

**References**

1. Abimbola, O. T. (2015). Sì nínú ẹ̀hun èdè Yorùbá. *AJOLL: Ago-Iwoye Journal of Languages and Literary Studies*. The Department of Nigerian and Foreign Languages and Literatures, Faculty of Arts, Olabisi Onabanjo University. Ago-Iwoye, Ogun State. Pp. 1 – 19.
2. Abimbola, O. T. (2019). Focusing in the Information Structural Categories of Aika, Akoko Area, Nigeria. Ph.D. Dissertation, the Department of Linguistics and African Languages, University of Ibadan, Ibadan, Oyo State, Nigeria.
3. Abimbola, O. T. (2024). Ìsọ̀rí Ọ̀rọ̀. *A Compendium of General Nigerian Studies. GNS 104: Use of Yoruba and culture: basic Communication Concept*. Pp. 290 – 305. Lagos State University Centre for General Nigerian Studies (GNS), Lagos.
4. Adékẹ́yè (2016). *Gírámà Tuntun ní Èdè Yorùbá*. Aba: NINLAN.
5. Ajiboye, O. A. (2024). *New Horizons in Yoruba Grammar*. Ibadan: Kingdom Arts Publishing.
6. Aremu, D., & Weisser, P. (2024). Prosodically determined coordinator placement in Yorùbá. *Glossa: a journal of general linguistics*. Open library of humanities.
7. Awobuluyi, O. (1978). *Essentials of Yoruba Grammar*. Ibadan: Oxford University Press.
8. Awobuluyi, O. (2008). *Ẹ̀kọ́ Ìṣẹ̀dá-ọ̀rọ̀ Yorùbá*. Akure: Montem Paperbacks.
9. Bámgbóṣé, A. (1990). *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. Ibadan: University Press PLC.
10. Ìlọ̀rí, J. F. (2010). Nominal Constructions in Igálà and Yorùbá. Ph.D. Thesis. Department of Linguistics and Languages, Adekunle Ajasin University, Akungba-Akoko.
11. Ìlọ̀rí, J. F. (2012). Issues in the Categorial status of 'Òun' in Yorùbá. *Journal of Universal Language.* 35 – 64.
12. McIntyre, A. (2015). Functional Categories (handout 2: Seminar English Syntax) accessed on 2/8/2024.
13. Rizzi, L., & Cinque, G. (2016). Functional Categories and Syntactic Theory. *Annual Review of Linguistics*. Online linguist.annualreviews.org 2016:139-163. Downloaded 2/8/2024.
14. Yusuf, O. (1980). Conjunction in Yoruba. Seminar paper in the Department of Linguistics and Nigerian Languages, University of Ilorin, Ilorin.
15. Yusuf, O. (1999). *Gírámà Yorùbá Àkọ̀tun ní ìlànà ìṣípayá onídàrọ*. Àtúnṣe kejì. Ìjẹ̀bú-Òde: Shebiotimo Publications.
16. Yusuff, A. (2006). *Ojúlówó Gírámà Yorùbá*. Akoka: Institute ofAfrican and Diaspora Studies, University of Lagos

Copyright © 2025: by the author/s. This article is licensed and distributed under an Attribution-NonCommercial-ShareAlike 4.0 International (CC BY-NC-SA 4.0)